# OUNJẸ ÌYÈ

## Johannu 6:22-65

### ẸKỌ 94 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Ẹ máṣe ṣiṣẹ fun onjẹ ti iṣegbé, ṣugbọn fun onjẹ ti iwà titi di ìye ainipẹkun" (Johannu 6:27).**

**I Awọn Ti N Wá Jesu nitori Akara ati Ẹja**

1. Ọpọ eniyan pada si Kapernaumu lati wá Jesu, Johannu 6:22-25
2. Jesu bá wọn wí nitori wọn n wa A ki wọn le ri akara ati ẹja, Johannu 6:26-29
3. Ọlọrun ti fi Manna tootọ fun ni lati Ọrun wá, Johannu 6:30-35

**II Iye ni Ohun Pataki ti Jesu Mú Wá**

4. O ṣeleri ajinde si iye ti ko ni ipẹkun fun awọn ti Baba ti fi fun Un, Johannu 6:36-40
5. Awọn Ju n kùn nitori Jesu wi pe, "Emi ni onjẹ," Johannu 6:41-43
6. Awọn ti Baba ba fà nikan ni o le wa sọdọ Jesu, Johannu 6:44-46

**III Jesu Tẹnu Mọ Ọn pe Oun Paapaa ni Ounjẹ Iye naa**

7. O tẹnu mọ ileri iye ti ko nipẹkun fun awọn ti o gba A gbọ́, Johannu 6:47, 48; 1:12
8. "Onjẹ iye" naa n fun ni ni iye o si n mu ni wà laaye, Johannu 6:49-51
9. Wọn gbọdọ jẹ ẹran-ara Rẹ ki wọn si mu Ẹjẹ Rẹ, Johannu 6:52-58; Ẹksodu 12:8; Johannu 1:29
10. Jesu ṣe alaye "ọrọ lile" naa, Johannu 6:59-65.

## ALAYE

**Ounjẹ ti N Ṣegbe**

Nigba ti ọpọ eniyan n wá Jesu kiri ni ọjọ keji ti o bọ́ ẹgbẹẹdọgbọn eniyan, Jesu mọ ọkàn wọn O si wi pe, "Ẹnyin nwá mi, ki iṣe nitoriti ẹnyin ri iṣẹ àmi, ṣugbọn nitori ẹnyin jẹ iṣu akara wọnni, ẹnyin si yó," Lẹyin naa O lo iṣẹ iyanu ti bibọ́ ẹgbẹẹdọgbọn eniyan naa lati fi kọ́ wọn idi pataki ti a fi rán Oun wá si ayé yii, -- eyi ni lati bọ́ ọkàn eniyan. A gbọ́ ti ara má gbọ́ ti ẹmi ni eniyan jẹ́ ni gbogbo iṣe rẹ̀. Ninu Iwaasu lori Oke, Jesu kọ́ ni pe ẹmi ju ounjẹ ati aṣọ lọ. Oun si tun kọ ni pe, "Igbesi aiye enia ki iduro nipa ọ̀pọ ohun ti o ni" (Luku 12:15). Ayé kún fun iwọra ati iwa ipa lonii nitori eniyan n fẹ ni ọ̀pọ ohun rere ti ayé yii, o si ti ṣá Ounjẹ Iye tì, ti ọkàn rẹ̀ n fẹ́ paapaa.

"Ẹ máṣe ṣiṣẹ fun onjẹ ti iṣegbé, ṣugbọn fun onjẹ ti iwà titi di ìye ainipẹkun." Ohun gbogbo ti eniyan kó jọ lati igba èwe rẹ̀ titi dé ọjọ́ ikú, jẹ́ "onjẹ ti iṣegbe." Ohun igba diẹ ni, o si fẹrẹ kọja lọ. Ara paapaa ti eniyan fi ohun gbogbo ti o ni fún yoo pada si erupẹ lai pẹ. Ẹmi nikan ni ki i kú ti yoo si wà laelae. Nitori naa o ṣe pataki pupọ ju lọ ki a ṣe itọju ẹmi ju bi a ti le ṣe itọju ara lọ.

**Ounjẹ Iye**

"Enia kì yio wà lãye nipa akara nikan bikoṣe nipa gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu Ọlọrun jade wá" (Matteu 4:4). Lojoojumọ ni eniyan maa n jẹ ounjẹ ti n fun ara ni okun. Bi ara ti n gba agbára lati inu ounjẹ, bẹẹ gẹgẹ ni ọkàn wa n gba agbára lati ọdọ Jesu, ti I ṣe Ounjẹ Iye. Dafidi wi pe, "Li alẹ, li owurọ, ati li ọsan, li emi o ma gbadura" (Orin Dafidi 55:17). Bi a ba kuna lati jẹ Ounjẹ Iye a o di alailagbara nipa ti ẹmi. Lai pẹ a o kiyesi pe ọta n bori wa, a kò si ni agbara lati dojukọ ọfa rẹ̀. Nigba ti Jesu gbadura fun ogoji ọsan ati ogoji oru, ebi pa A, aarẹ si mu Un, ṣugbọn agbara Rẹ̀ nipa ti ẹmi pọ̀ si i. Eṣu dojuja kọ Ọ lọna gbogbo, ṣugbọn pẹlu oore-ọfẹ ati agbara Jesu fọ́ gbogbo itẹgun eṣu ati ọrọ ẹtan rẹ̀. O si jade ni aginju pẹlu agbara Ẹmi.

A fẹ́ lati maa wo ẹni ti ara rẹ̀ dara jọjọ, -- ẹni ti o dabi pe ohun gbogbo ni a fi tẹ ẹ lọrun. Onigbagbọ́ a maa fẹran ẹni ti o ti walẹ̀ jìn, ti o ti ṣe eto ile ẹmi rẹ̀ daradara, ti o si n bọ́ ọkàn rẹ̀ nipa ti ẹmi lojoojumọ. Dajudaju Oluwa pẹlu yoo ni inu-didun lori ẹni ti a ba ti fi Ẹjẹ Ọdọ-agutan wẹ ọkàn rẹ̀ mọ́, ti o si n jẹ manna ọrun lojoojumọ.

Nigba ti Oluwa kọ́ awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ bi a ti i gbadura pe, "Fun wa li onjẹ õjọ wa loni", itumọ rẹ̀ jinlẹ ju ounjẹ ti a ni lori tabili wa lojoojumọ lọ. A n fẹ manna ti o pamọ ni ti o n mú ọkàn wa dagba ti o si n fun ni ni agbara lati la gbogbo iṣoro ti o wà lọna wa kọja.

**Ounjẹ Ẹmi**

Isaiah sọ bayii pe, "Nitori kini ẹ ṣe nná owo fun eyiti ki iṣe onjẹ? ati lãla nyin fun eyi ti ki itẹnilọrun? ni gbigbọ́, ẹ gbọ́ t'emi, ki ẹ si jẹ eyi ti o dara, si jẹ ki inu nyin dùn ninu ọra" (Isaiah 55:2). Nipa bayii o n tọka si i pe ounjẹ ẹmi ṣe pataki ju ounjẹ ti ara lọ. Ara wa yoo pada si erupẹ ṣugbọn ẹmi wa yoo wà laaye titi lae.

Iye ni o le mu iye duro. Ounjẹ ti ara paapaa jade lati inu awọn nnkan ti ó wà laaye. Ounjẹ kò jade lati inu awọn ohun ti kò ni iye ninu. Bakan naa ni nipa ti ẹmi, a fi Jesu, orisun iye ni O le fi iye fun wa. O wi pe, "Emi ni onjẹ ìye nì ti o ti ọrun sọkalẹ wá; bi ẹnikẹni ba jẹ ninu onjẹ yi, yio yè titi lai."

**Manna**

Manna ti Oluwa fun awọn Ọmọ Israẹli ni aginju gbọdọ ti ni ohun wọnni ti o yẹ fun idagbasoke ti ara. On ni wọn jẹ fun ogoji ọdun. Oluwa ti o dá ara wa pẹlu gbogbo ẹ̀yà rẹ̀, mọ ohun ti o tọ́ lati fi sinu manna kékèké naa, eyi ti o dabi ìrì dídì, lati mu egungun ati ẹran ara dagba. Manna naa ni o dipo akara, ẹran, eso ati ewebẹ. Jesu ti I ṣe Manna tootọ lati Ọrun ni ohun gbogbo ti a fẹ lati gbé ẹmi wa ró ki O si fun wa ni agbara ati okun ninu Oluwa. Ọna iyanu ni manna gbà dé ọdọ wọn, bakan naa si ni ounjẹ ẹmi ti wa.

**"Ounjẹ ọrun mã bọ mi titi lailai."**

**Kíkùn**

O dabi ẹni pe iwa eniyan ko yipada lati bi ọpọlọpọ ọgọrun ọdun sẹyin. Awọn Ọmọ Israẹli kun pe manna ti Oluwa fun wọn lọjọọjọ. Ọkàn wọn korira ounjẹ futẹfutẹ naa.

Nigba ti Jesu n sọ fun awọn ọmọ-ẹyin rẹ̀ pe Oun ni Ounjẹ Iye naa ati pe, "Bikoṣepe ẹnyin ba jẹ ara Ọmọ-enia, ki ẹnyin si mu ẹ̀jẹ rẹ̀, ẹnyin kò ni ìye ninu nyin," wọ́n kùn wọn si wi pe, "Ọ̀rọ ti o le li eyi, tani le gbọ́ ọ?"Lati igba naa lọ, pupọ ninu awọn ọmọ ẹhin Rẹ̀ pada sẹyin wọn kò si ba A rin mọ́. Lonii awọn eniyan n wi pe Ihinrere le jù, ọna naa há; wọn kò le rìn ín. Wọn n kùn si eto irapada nla Ọlọrun, wọn si n kẹyin si i. Wọn n kọ̀ lati gba Ounjẹ Iye naa, lati jẹ ninu Ọdọ-agutan ti a ti pa lati ipilẹṣẹ ayé, nipa bẹẹ wọn si sọ ireti Ọrun ati iye ainipẹkun nù. Ki Ọlọrun ki o ràn wá lọwọ ki awa ma ṣe kùn, ki a ma ba ṣegbe sinu aginju gẹgẹ bi o ti ri fun awọn Ọmọ Israẹli!

Akoko kan wà ti Dafidi ṣe ilara si ilọsiwaju awọn eniyan buburu, o si ro pe lasan ni oun ti wẹ ọkàn oun mọ́, a fi igba ti o lọ si ile Ọlọrun ti o si jẹ ounjẹ Ọrun. Nigba naa ni òye rẹ̀ nipa ti ẹmi ṣi, o si ri igbẹyin wọn (Orin Dafidi 73).

**Apẹẹrẹ**

Ṣiwaju ikú Rẹ̀, igba ti Jesu ti jẹ Ase Irekọja tán pẹlu awọn ọmọ-ẹyin ni alẹ́. O mú akara, O sure si i, O si bu u, O si fi i fun awọn ọmọ-ẹyin, O wi pe, "Gbà, jẹ; eyiyi li ara mi," O si mu ago, O dupẹ, O si fifun wọn, O wipe, Gbogbo nyin ẹ mu ninu rẹ̀; Nitori eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun, ti a ta silẹ fun ọ̀pọ enia fun imukuro ẹ̀ṣẹ" (Matteu 26:26-28). Awa naa le ri bi o ti yẹ lati jẹ lara Ounjẹ otitọ naa ti o ti Ọrun wá ki a ba le ni iye ainipẹkun ninu wa.

**Ìpè Naa**

"Ẹniti o ba si tọ̀ mi wá, emi ki yio ta a nù, bi o ti wù ki o ri." Awọn talaka ayé yii ni wọ́n ti le kuro pẹlu ebi nigba pupọ ni ọdọ awọn ti o ni lọwọ lati fun wọn jẹ. Ṣugbọn Jesu ki i lé ẹni ti ebi n pa pada, i baa jẹ́ ọlọrọ tabi talaka, ẹrú tabi ominira, dudu tabi funfun. Ihinrere wà fun ẹnikẹni ti o ba fẹ́.

**AWỌN IBEERE**

1. Ounjẹ wo ni a n pè ni ọ̀pá iye?
2. Taa ni Ounjẹ Iye naa?
3. Ounjẹ wo ni Ọlọrun fi fun awọn Ọmọ Israẹli ni aginju?
4. Njẹ wọn jẹ Ounjẹ tootọ nì lati Ọrun?
5. Ki ni ṣe ti awọn eniyan naa fi kùn?
6. Ki ni ṣe ti ọpọlọpọ eniyan fi pada lẹyin Jesu?
7. Ki ni itumọ ki a jẹ ẹran-ara ki a si mu Ẹjẹ Ọmọ Ọlọrun?